AWON OHUN PATAKI NINU IWE OSE YI

Zik ati Iyawo rẹ ti de
Oju iwe 1
Igbimọ Ijọba Ijẹsa sepejọ
Oju iwe 1
Ẹ ranti adugbo Orogba
Oju iwe 2
Ọrọ nipa Owori (Tax)
Oju iwe 3

# IRANỌ ★ OBOKUN

Esi ọrọ Ojẹngbẹdẹ
Oju iwe 4
A ko fẹ alako
Akẹju ni b'ọmọ jẹ
Oju iwe 5
Oju iwe 6
A fẹ ki Ọbabirin de Ilesa
Oju iwe 7
Ibiti Ọna yio de
Oju iwe 8

Vol 4 No 165 ILESHA MONDAY DECEMBER 5 1955 IYE OWO: TORỌ

## WON ÞE GBE EGBE ỌMỌ IBILE IJẸSA DIDE



ALAIYELUWA ỌBABIRIN ILẸ GẸSI

Eto ti nlọ lọdọ gbogbo awọn ijọba ijọba Nigeria lori eto bi wọn yio ti ṣe gba oa ati ọkọ rẹ ni alejo loṣu to nbọ: Ijọba Ẹkun Ila Orun (East) yio na ẹgbẹrun marundinlogoji poun (£35,000) ti Iwọ Orun (West) yio na ẹgbẹrun ọna ọgọrun:

### AZIKIWE ATI IYAWO RẸ TI ILU ỌBA DE

Ni ọgbọnjọ oṣu to koja ni Ọlọla Nnamdi Azikiwe ati iyawo rẹ de lati ilu Oyinbo.

Lọjọ na lo doṣu kẹta gere ti Ọlọla na ti lọ fun anfani ilẹsiwaju ijọba rẹ.

Iyawo rẹ tiwa ninu Oyinbo lati ọdun 1951 gẹgẹbi akẹkọ lẹhin igbati o ti di iya ọmọ mẹrin, O de pẹlu oyẹ (B.Sc) giga ninu ẹkọ lati ile ẹkọ ti npe ni Howard University ni Amerika.

### IGBIMỌ IJỌBA IJẸSA YIO ṢE IPADE LONI

Lati inu ọsẹ to kọja ni iwe ti dọwọ awọn kanselọ ati Ijoye to wa ninu igbimọ ijọba akopọ ile Ijẹsa pe wọn yio pade lọjọ kanun oṣu yi.



ỌLỌLA J. O. FADAHUNSI

On ni alaga igbimọ ijọba akopọ ile Ijẹsa. Igbimọ na yio ṣe ipade loni. Eto inawo tọdun to mbọ pẹlu iṣẹ ti wọn yio ṣe loni.

## Titan Ina Monamona Ni Ilu Ilesa

Eyi yi ni lati sọ fun gbogbo awọn ẹniti o ba ti waya ile rẹ fun ina titan wipe ki o lọ san (£1) Poun kan fun ọga onina ni ibi iṣẹ wọn ni ọna Oṣogbo lati ọjọ keje, oṣu kejila ọdun yi (7th December 1955) Nigbati awọn eleto onina yio bẹrẹ lati gba owo mimu waya wọ ile rẹ lati le jẹki o tan ina. Eyi bẹrẹ ni Wednesday ati Friday ni agogo mejọ titi idi agogo mejila ni ọsọsẹ. Jọwọ mase jafara lati ṣe eyi ki o ba le tan ina ile rẹ ni akoko ti o ba fẹ.

J. M. AJAYI OBE
CHAIRMAN
Electricity & Water Committee

Sr A. O. ABIỌLA
Ag. Secretary
ILESHA URBAN DISTRICT COUNCIL ILESHA

## MEETING OF SHARE HOLDERS

Notice is hereby given that a meeting of the Shareholders of the Ijesha Press Ltd., intended to be held on the 6th December had been posponed to Friday 16th. December 1955 at Obokungbusi Hall at 5 p.m.

AGENDA:—

1. Minutes & Matters arising
2. Audito'r Report
3. Press Progress
4. General

## BOARD. OF DIRECTOS' MEETING

Another meeting of the Board of Directors Ijesha Press Ltd. takes place on Friday, December 9, 1955 at 5: 30 p.m. at the Press Workshop premisses

AGENDER:—

1. Minutes & Matters Arising
2. Auditors' Report
3. General.

S. A. OJO
Ag. Secretary.



ỌLỌLA OBAFẸMI AWOLỌWỌ

Wọn fiwe sode pe ẹgbẹrun poun lọna ọgọrun (£100,000) ni Ijọba Ẹkun Iwọ Orun Nigeria yio na lasiko ibẹwo Ọbabirin Gẹsi.

### IJỌBA ẸKUN IWỌ ORUN YIO NA £100,000

Igbimọ eleto inawo ti Ẹkun Iwọ Orun Nigeria ti fọwọ si ẹgbẹgbẹrun poun lọna ọgọrun (£100,000) afikun inawo lati na lasiko ibẹwo Ọbabirin ilẹ Gẹsi ninu oṣu kini ọdun to nbọ.

Eto ibiti awọn oniwe irohin ti yio ma kọ irohin ilọsokesodo Ọba na yio na ijọba ni ẹgbẹrun marun poun. Wọn yio ra mọtọ ti ọba yio mo gun kiri ni ẹgbẹrun mẹrin abọ. Wọn yio fi ẹgbẹrun mejila poun se ọsọ si ọna igboro ati awọn ile ijọba

Wọn tun fi ọpọlọpọ owo silẹ fun awọn eto miran Nipa bẹ apapọ gbogbo owo ti wọn yio na jẹ ẹgbẹrun poun lọna ọgọrun:

## IPINU AINIGBẸKẸLE ẸNI

A ri ẹda iwe yi gba lati ọwọ Itagunmodi Local Council lọsẹ to kọja, Ẹda iwe na ti kọja sọwọ alaga ijọba ilẹ Ijẹsa. sọwọ Olubẹwo iṣejọba ilẹ Ijẹsa gẹgẹ bi o tiṣe dọwọ awa na.

Iwe na sọpe

"Iwe kan ti wọn tikọ ni ọjọ kẹtalelogun oṣu kẹjọ ọdun yi lati ọwọ Akoko Matthew ati Oko Ọgbeni dọwọ igbimọ Itagun, wọn si ka siwọn leti ni ipade ti wọn ṣe ni ogunjọ oṣu kẹsan ọdun yi.

"Ninu iwe na, awọn meji to fọwọ si iwe ti wọn fi yan Ọgbeni M.O Fapohunda ni Kanselọ sọpẹ awọn koni igbẹkẹle ninu rẹ mọ nitoripe o ti fẹgbẹ ti awọn forukọ rẹ yan silẹ lọ sinu omiran.

"A ko ṣe iṣẹ kankan lori iwe na nitoripe awọn to kọwe kosi lati jẹri si nigbati Kanselọ Fapohunda mọ pe wọn ko gbagbọ pe awọn to yan on lo kọ iwe na. O ni ki i ṣe aṣa pe wọn ni lati yọ ẹnikẹni to ba ti bọsinu ẹgbẹ miran ni Kanselọ lẹhin igbati o ti fẹgbẹ omiran wọle. Lẹhin eyi, igbimọ sọ fun akọwẹ ko pe awọn to kọwe na si ipade tọjọ miran.

"Si ipade tọjọ kerundogun oṣu kẹwa awọn to kọwe na wa ṣugbọn Kanselọ Fapohunda ko wa. Wọn ye ipade na pe awọn lo kọ ohun to wa ninu iwe ati pe ohun ti awọn kọ awọn fẹ ki wọn to kọ. Ariyanjiyan wa ni ipade na lori pe Kanselọ Fapohunda nilati wa nipade ki igbimọ to pinu lori ọrọ rẹ.

"Ṣugbọn awọn to pọju fẹnu si pe ki igbimọ ṣiṣẹ lori ọrọ na. Lẹhin na Kanselọ Ṣiyanbọla Oguntade daba, Kanselọ Akinwale si fara mọ pe ki igbimọ na faramọ ọrọ awọn to fọwọ siwe idibo Kanselọ Fapohunda ti wọn si kọwe pe niwọn igbati o tile fẹgbẹ ti awọn forukọ yan silẹ awọn ko nigbẹkẹle si mọ, awọn ko si fẹ mọ ni aṣoju ni Itagun ati ninu igbimọ akopọ ilẹ Ijẹṣa. Ati pe ki wọn kọwe nipa rẹ si awọn alaṣẹ gbogbo.

Oloye D. A Haastrup tako aba na, Kanselọ J.J Babatunde si kin lẹhin pe ki ipinu di igbati Kanselọ Fapohunda yio wa ni ipade. Lasiko idibo le aba na lori awọn marun faramọ atako, mẹwa faramọ aba gidi, enia mẹta kọ lati faramọ tọtun tosi."



ỌGBẸNI E. A. ỌKẸ

On jẹ ọkan ninu awọn to da ẹgbẹ Ọmọ Ibilẹ Ijẹṣa silẹ. On na lo kowe lọsẹyi pe oyẹ ki ẹgbẹ na tun ji dide lati ma jafun ire ilẹ Ijẹṣa. Wọn fi ọjọ Ìpade si ọjọ kẹwa oṣu.

## IBERE LATI ỌDỌ OLOTU
[Lati Ọwọ Gabrel A Dada)

Inu mi yio dun, si Olotu iwe irohin wa ọsọsẹ ti a npe ni Irawọ Obokun ba le dami lohun ibere yi loruko idile Risawẹ.

Ibere na ni wipe ṣe o tọ lati tun bẹrẹ nigba keji lati ma tako ara wa gẹgẹ bi Ọgbẹni Ezekiel Gureje ti kọ sinu iwe 7;11;52 ati 21;11;55 wipe awọn ẹbi Risawẹ, ko pe awọn idile Gureje Asọgbẹ si ipade ọmọ ile nigbati awọn nseto lati fi orukọ idile ti wọnti ọtọ oye jiji sọwọ si Ijọba Ibilẹ?

Inu wa yio dun ti Olotu ba lefun wa ni idaniloju wipe ti a ba bẹrẹ tia sọ sinu iwe Irawọ Obokun ipo Ijaga Gureje nile oloye Risawẹ, eyi ko ni mu iparun ba iwe irohin wa yi, bi ti igba isaju ti ọpọlọpọ enia nsọ kiri bayi wipe ọran oye Risawẹ o pa iwe irohin wa ti a npe ni Engadi run ni ilẹ Ijẹṣa.

"Bi ẹru ba nba nyin ki ẹ wi ẹru kan ko ba ọmọ Ọmọle.

Inu wa yio dun ti Olotu Irawọ Obokun ba le fun wa ni esi iwe yi ninu iwe irohin rẹ lọsẹ to nbọ.

AKỌLE OLOTU:- wo akọle olotu loju iwe 5.

## ESI SI ỌRỌ ỌGBẸNI OJONGBẸDẸ
Lati ọwọ Kanselọ J. O. Ọlọwẹ Itagun

Inu mi yio dun pupọ ti Olotu ba gba mi laye lati fesi si ọrọ ti J. G. Ojongbẹdẹ sọ ninu Irawọ Obokun ti ọjọ kẹrinla oṣu to kọja ki emi le fun ni alaye diẹ nipa bi wọn tiṣe pin ilẹ Ijesa ni onilujulu sinu akamọ ijọba kọkan.

Ijọba mọ ohun to nṣe, ki ise ara Itagud lo fẹnu wọn sọpe ki wọn pin Gada ati Aye sinu akamọ tiwọn, bi kosk lori eto inawo ti ijọba lori rẹ pinu wọn bẹ.

Mo rope lati Gada si Ibod Itagun lọse ọna to de ọdọ yio? bẹni tabi bẹkọ? nitori eyi ni ijọba ṣe ge Gada mọ Itagun nitoripe anfani ti ẹ njẹ Itagun lo njẹki ẹ jẹ anfani na ki etun o ṣe iwadi lọdọ awọn ijọba Ki wọn to ṣe ko si ilu kọkan ti wọn pe nitoripe ijọba gbọn pupọ, nitori idi eyi ni awa gẹgẹ bi ilu Itagan tiṣe dide si ọrọ na pe ijọba ti pin ful ara wọn. Kiṣe asise rara o.

Nipa ti Iyere ti o kun ba nṣe ni o ba wadi kio to sọ bẹ nṣe ni o ba bere bi ọrọ na tiṣe ribẹ. Idirẹ nipe inu akamọ ijọba Itagun ni wọn pin Iyere si tẹlẹ ṣugbọn nigbati Itagun nfigba gbogbgo ja lori ọrọ oye Lọja ati Lọyin ni Ọgbẹni Akindele Ojo yọ Iyere kuro ni Itagun.

Ki o tun wadi eyi lọdọ Ọgbẹni Akindele Ojo.

Ni ipari ọrọ mi adura mi wipe ki Ọlọrun jẹki iṣẹ wa to wa jijẹ. Abọ mi re o.



AWỌN EBI AGBO ILE RISAWẸ, ILEṢA

Ninu iwe wa ọsẹ yi, Ọgbẹni Gabriel A. Dada, ẹniti o sọpe on jẹ AKỌWE idile Oye Risawẹ Ilesa, bere lorukọ idile na lọwọ Olotu Irawọ Obokun pe ṣe o tọ lati tun bẹrẹ nigba keji lati ma tako ara lori ọrọ Risawẹ. Olotu ti dahun loju awẹ karun pe iwe irohin ko fẹ atako bi ko ṣe alaye tabi asọye.

